# IPALARADA AWỌN ENIYAN MIMỌ́
## 1 Tẹssalonika 4:13-18; 5:1-24
## ẸKỌ 412 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Eyiyi li awa nwi fun nyin nipa ọ̀rọ Oluwa, pe awa ti o wà lãye, ti a si kù lẹhin de atiwá Oluwa, bi o ti wu ki o ri ki yio ṣaju awọn ti o sùn" (1 Tẹssalonika 4:15).**

**I Itunu Nipa Ti Awọn Ti O Sùn**

1 Awọn ti o sùn ninu Kristi ni yoo kọ jinde, 1 Tẹssalonika 4:13-16; 1 Kọrinti 15:23

2 A o gba awọn eniyan mimọ́ ti o wà laaye soke pẹlu wọn, 1 Tẹssalonika 4:17; 1 Kọrinti 15:51, 52

3 A fi Iwe Mimọ́ fun wa fun itunu wa, 1 Tẹssalonika 4:18; 5:11; 2 Kọrinti 1:3, 4

**II Wiwa Ni Imurasilẹ De Bibọ̀ Rẹ̀**

1 Yoo de bi olè ni oru, 1 Tẹssalonika 5:1-4; Matteu 24:42-51

2 Onigbagbọ́ ni lati maa ṣọna, 1 Tẹssalonika 5:5-10; Matteu 25:1-13

**III Ọrọ Iyanju Fun Awọn Onigbagbọ́**

1 Ẹ bu ọlá fun awọn olori yin, 1 Tẹssalonika 5:12-15; Heberu 13:17

2 Ẹ maa gbadura ki ẹ si maa dupẹ, 1 Tẹssalonika 5:16-20; Filippi 4:6

3 Ẹ takete si ohun ti i ṣe ibi, ki ẹ si di eyi ti o dara mu ṣinṣin, 1 Tẹssalonika 5:21-24; Orin Dafidi 34:14; Romu 12:9

### ALAYE

**Iṣẹlẹ Nla Meji**

"Ipadabọ Kristi lẹẹkeji", tọka si iṣẹlẹ nla meji, Ekinni ni Ipalarada Ijọ, ni akoko igba ti kikidá awọn ti o ba murasilẹ nikan ni yoo ri Kristi, a o gbà wọn soke lati pade Rẹ̀ ni awọsanma. Iṣẹlẹ Keji ni Ifarahàn Kristi, nigba ti Oun yoo pada bọ̀ pẹlu awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ lati gbé Ijọba Rẹ̀ kalẹ ninu ayé - Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun. Laaarin akoko Ipalarada Ijọ Ọlọrun ati Ifarahàn Kristi, ni Ase Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan yoo ṣẹlẹ ni Ọrun ati lori ilẹ ayé ni Ipọnju Nla yoo si wà.

Ipalarada Ijọ Ọlọrun ni gbigba awọn Iyawo Kristi soke - awọn ti o ti mura tán – lati inu ayé yii, si ibi ti Jesu ti pese silẹ fun wọn, ki wọn le wà ni ìdipọ pẹlu Rẹ̀ ni ibi Ase Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan. Jesu wi pe, "Emi nlọ ipese àye silẹ fun nyin. Bi mo ba si lọ ipèse àye silẹ fun nyin, emi o tún pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu" (Johannu 14:2, 3).

**A O Jinde**

Pupọ iboji lo wà laisi itọju: a ti pa ọpọlọpọ akọsilẹ nipa awọn oku ti o ku rẹ́, a ti gbagbe awọn ti o ti lọ ṣaaju; o ṣeeṣe ki a ti sun awọn eniyan ninu iná, wọn ti le fẹ́ eeru wọn kaakiri tabi ki wọn ti rì sinu omi; ṣugbọn kò si ohun ti yoo ṣe idena fun okú ninu Kristi ti ki yoo fi lè jade wa nigba ti Ipè Ọlọrun bá dún. Ẹkọ Ijinlẹ n sọ fun wa pe kò si ohun kan ti o le parun patapata laijẹpe o fi amì kan silẹ. Bi o tilẹ jẹ pe ara awọn eniyan mimọ́ pada si erupẹ, sibẹ, lati inu ilẹ naa wa ni olukuluku ọmọ Ọlọrun yoo ti jade wá pẹlu ara ologo, ara ajinde, nigba ti Oluwa yoo sọkalẹ lati ọrun wa ti oun ti ariwo, pẹlu Ipe Ọlọrun. Jesu wi pe "Wakati mbọ, ninu eyiti gbogbo awọn ti o wà ni ìsà okú yio gbọ́ ohùn rẹ̀, nwọn o si jade wá" (Johannu 5:28, 29).

Eyi jẹ ohun ti o dá Jobu loju nigba ti o kigbe soke pe "A! Ibaṣepe a le kọwe ọ̀rọ mi nisisiyi, ibaṣepe a le dà a sinu iwe! Ki a fi kalamu irin ati ti ojé kọ́ wọn sinu apata fun lailai. Ati emi, emi mọ̀ pe Oludande mi mbẹ li ãyè, ati pe On bi Ẹni-ikẹhin ni yio dide soke lori erupẹ ilẹ. Ati lẹhin igba awọ ara mi, ti a ti ke e kuro bi iru eyi, ati laili ẹran ara mi li emi o ri Ọlọrun. Ẹniti emi o ri fun ara mi, ti oju mi o si wò, ki si iṣe ti ẹlomiran, ọkàn mi si dáku ni inu mi" (Jobu 19:23-27).

**Ajinde Kin-in-ni**

Gbogbo okú bẹrẹ lati Adamu titi de opin ayé ni a o ji dide, "Ṣugbọn olukuluku enia ni ipa tirẹ̀: Kristi akọbi; lẹhin eyini awọn ti iṣe ti Kristi ni bibọ rẹ̀" (1 Kọrinti 15:23). Ajinde awọn olododo ti a n pè ni, "ajinde ekini" pin si oriṣiriṣi ipa; eyiiyi ni pe, Kristi gẹgẹ bi akọso, jade wá ṣaaju ni apẹẹrẹ ikore ti yoo tẹlee. A sọ fun wa pe nigba ti Jesu ku, "awọn isà oku si ṣi silẹ; ọ̀pọ oku awọn ẹni mimọ́ ti o ti sùn si jinde, nwọn ti inu isà okù wọn jade lẹhin ajinde rẹ̀, nwọn si wá si ilu mimọ́, nwọn si farahàn ọ̀pọlọpọ enia" (Matteu 27:52, 53). Ireti wa nipa ajinde kò duro lori igbagbọ́ nikan, ṣugbọn o duro lori ẹri ti o daju pe Jesu jinde kuro ninu oku, ki i si ṣe Oun nikan, ṣugbọn ọpọlọpọ awọn eniyan mimọ́ pẹlu Rẹ̀. Nipa bayii, pẹlu gbogbo akọso ti a ti gbà wọle, a ni idaniloju ikore ti yoo tẹle e.

Ni bibọ̀ Rẹ̀, a sọ fun wa pe awọn okú ninu Kristi ni yoo kọ jinde. "Ipè yio dún, a o si ji awọn okú dide li aidibajẹ, a o si pawalara dà" (1 Kọrinti 15:52). Fun igba pipẹ ni a ti n lo ipè lati ji awọn ọmọ-ogun ti o ti sùn dide, ṣugbọn ọjọ nla wo ni ọjọ yii yoo jẹ nigba ti Ipè Ọlọrun yoo ji gbogbo awọn okú ti o ti kú ninu Kristi dide lati inu erupẹ ilẹ. Lẹsẹkẹsẹ ti Onigbagbọ́ ba kú ni ẹmi wọn n lọ si Ọrun. Nigba ti Kristi ba padabọ ni igba Ipalarada, a o fi aiku wọ awọn ọkàn wọnyii pẹlu ara ti a ti ji dide kuro ninu okú; olukuluku wọn yoo gbé ara ti wọn bọ́ silẹ nigba ikú wọ̀. Ara ajinde yii "ni yio sọ ara irẹlẹ wa di ọ̀tun ki o le bá ara ogo rẹ̀ mu" (Filippi 3:21).

Awọn ti o wà laaye, awọn eniyan mimọ́ aṣẹgun ni a o "palarada, lọgan, ni iṣẹju, ni a o gba wa soke pẹlu wọn sinu awọsanma, lati pade Oluwa li oju ọrun." Nipa bayii Ipalarada Ijọ Ọlọrun ti i ṣe ikore nla ti Ajinde Ekini, jẹ ipalarada awọn eniyan mimọ́ aṣẹgun ti o wa laaye ati ti awọn okú ninu Kristi.

**Ikilọ**

"Ẹ jẹ ki a mã ṣọna, ki a si mã wà li airekọja." Awọn alafara ati awọn alainaani, wọn tilẹ le pe ara wọn ni Onigbagbọ́ sibẹ wọn wà ninu ewu nla, nitori nigba ti Ipè ba dún, a o fi wọn silẹ lọ. Jesu pa owe wundia mẹwaa gẹgẹ bi ikilọ fun awọn wọnni ti o kuna lati ṣe imurasilẹ ti o to fun bibọ Rẹ̀. Wo bi ijatilẹ naa yoo ti korò to fun awọn wọnni ti o lero lati ni ipin ninu igbeyawo naa ṣugbọn ti a ti ilẹkun mọ́ wọn sẹyin òde! Ta ni le fi oju ẹmi wo ikorò ọkàn awọn wundia alailọgbọn yii ti atupa wọn ti o n kú lọ n jẹri si ikuna wọn lati gba ororo Ẹmi ni igba ti i ṣe ọ̀sán, nigba ti Ọlọrun n tú Ẹmi Rẹ̀ jade sara eniyan gbogbo? A ti fi Ẹmi Mimọ́ wọ ọ bi?

Fi ọkàn ro ibẹru alailere ọmọ-ọdọ nì gẹgẹ bi o ti duro niwaju Ẹlẹda rẹ̀. Awawi rẹ̀ da a lẹbi, talẹnti rẹ̀ ti ko lo si wà lori tabili gẹgẹ bi ẹri idakẹjẹ fun iwa ainaani rẹ̀. Njẹ o le fi oju inu wo aini reti rẹ̀ nigba ti a n gbe e sinu okunkun biribiri pẹlẹ ẹkun ati ipayinkeke nitori pe o ṣe aibikita fun awọn anfaani ti a fi fun un? Njẹ o ha n lo talẹnti rẹ ninu iṣẹ iranṣẹ fun Ọba?

"Gbogbo nyin ni ọmọ imọlẹ, ati ọmọ ọsán: awa ki iṣe ti oru, tabi ti òkunkun" (1 Tẹssalonika 5:5). Ọrọ Ọlọrun n fun wa ni imọlẹ, ṣugbọn ti wa ni lati rin ninu rẹ̀. "Bi awa ba nrin ninu imọlẹ, bi on ti mbẹ ninu imọlẹ, awa ni idapọ pẹlu ara wa, ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo" (1 Johannu 1:7). Awọn ikilọ ti o wà ninu Bibeli pọ pupọ, ni pataki, awọn ti o n sọ bi o ti jẹ ohun danindanin to lati maa ṣọna fun bibọ Oluwa. Awa n ṣọna nipa fifi igbesi-ayé wa ṣe odiwọn Ọrọ Ọlọrun. Njẹ igbesi-ayé rẹ ha bá Ọrọ Ọlọrun dọgba tabi awawi ni iwọ n ṣe?

**Ihamọra**

"Ẹ jẹ ki awa, bi a ti jẹ ti ọsán, mã wà li airekọja, ki a mã gbé igbaiya igbagbọ́ ati ifẹ wọ̀; ati ireti igbala fun aṣibori." Ọmọ Ọlọrun tootọ ki i joko tẹtẹrẹ, kò tilẹ gbọdọ ni itẹlọrun si igbala nikan ki o si maa sùn. A gbọdọ jẹ onitara lati dagba ninu oore-ọfẹ, ati lati walẹ jin ninu Oluwa nipa jijẹ oloootọ ninu adura ati kika Ọrọ Ọlọrun. A gbọdọ fi isọdimimọ́ ti i ṣe iriri iṣẹ oore-ọfẹ keji ti a n ri gbà lọdọ Oluwa kún igbala. "Ki Ọlọrun alafia tikararẹ̀ ki o sọ nyin di mimọ́ patapata; ki a si pa ẹmi ati ọkàn ati ara nyin mọ́ patapata li ailabukù ni igba wiwa Oluwa wa Jesu Kristi" (1 Tẹssalonika 5:23). Ati pẹlu isọdimimọ́, ọmọ Ọlọrun tootọ gbọdọ ṣe afẹri Ẹmi Mimọ́ titi yoo fi ri i gbà gẹgẹ bi Jesu ti ṣeleri, ti awọn ọmọ-ẹyin si ṣe alabapin gẹgẹ bi a ti kọ ọ silẹ ninu Iṣe Awọn Apọsteli Ori keji, ki o to le di ọ̀kan ninu awọn Iyawo Kristi.

A gbọdọ "mã bu ọlá fun wọn gidigidi ninu ifẹ nitori iṣẹ wọn," awọn wọnni ti i ṣe "olori nyin ninu Oluwa." A n gbà wa niyanju lati maa tẹriba fun awọn alakoso wa nipa ti ẹmi: "Ẹ mã gbọ ti awọn ti nṣe olori nyin, ki ẹ si mã tẹriba fun wọn: nitori wọn nṣọ ẹṣọ nitori ọkàn nyin" (Heberu 13:17). Irẹlẹ ati itẹriba jẹ awọn iwa yiyẹ ti Iyawo Kristi. Nigba ti a ba n ba wa wi, ẹ jẹ ki a ranti pe

n ṣe ni a n pe wa lati "takéte si ohun gbogbo ti o jọ̀ ibi" (1 Tẹssalonika 5:22). Ẹ jẹ ki a yẹra patapata kuro lọna ewu, ki a si faramọ Ọlọrun timọtimọ "ki a si pa nyin mọ́ li ailabukù ni igba wiwa Oluwa wa Jesu Kristi" (1 Tẹssalonika 5:23).

**AWỌN IBEERE**

1 Awọn iṣẹlẹ meji wo ni a kó pọ̀ ninu bibọ Kristi lẹẹkeji?

2 Ṣe apejuwe Ipalarada.

3 Awọn wo ni yoo ni ipin ninu Ipalarada?

4 Sọ lẹsẹẹsẹ eto ajinde awọn oku.

5 Nibo ni ẹmi awọn okú wà nisisiyii? Njẹ wọn le mọ nnkan gẹgẹ bi ẹni ti o wà laaye?

6 Fi ajinde wé ikore.

7 Imurasilẹ wo ni a gbọdọ ṣe ki a ba le pade Oluwa ni ofurufu?

8 Ṣe apejuwe ipo ti Ijọ Ọlọrun ti Kristi kú fun wà.

9 Darukọ diẹ ninu awọn àmi bibọ Oluwa.

10 Ki ni a fi bibọ̀ Oluwa wé?